# IROHIN IMOLE

IMOLE ORE AIYE, TENI GBOGBO LAWA

No. 726 TUESDAY, JUNE 23, 1964 (2D)


## Awọn Ẹlẹwọn Meje Bẹlu Gbẹ

MAIDUGURI:- Laipẹ yi ni irohin de ọwọ wa lati ọwọ *onirohin* wa ni Maiduguri pe, awọn ẹlẹwọn meje kan ti nwọn njiya ẹṣẹ wọn ni ọgba ẹwọn ti Ijọba ibilẹ Borou ni ilu Maiduguri awọn ẹlẹwọn meje na salọ nibi ti awọn ẹlẹgbẹ wọn ti nṣa ori papa.

Irohin na fi ye wa pe gbogbo awọn ẹlẹwọn ti nwọn ko lọ si ori papa ni ọjọ na jẹ ọgbọn pẹlu awọn ti nma nsọ awọn ẹlẹwọn na mẹfa ti awọn ẹlẹwọn na si nsan papa na ṣugbọn lojiji ni awọn mejeje wọnyi rọra sa sinu igbo ṣu-u kan to wa lẹba p pa na ti nwọn si salọ.

Ninu awọn oluko awọn ẹlẹwọn na si tete ri ifura ti o sọ fun awọn ẹlẹgbẹ rẹ yoku pe on fura si pe ninu awọn ẹlẹwọn na ti salọ, lẹsẹkẹsẹ ni wọn bẹrẹ si wo gbogbo awọn ẹlẹwọn na yika ti awọn oluṣọ ẹlẹwọn na si fi igbe ta.

Lẹsẹkẹsẹ na ni nwọn Si ko ninu wọn sinu igbo to wa lẹba wọn lati lọ mu wa awọn ẹlẹwọn na, ṣugbọn larin wakati diẹ ti nwọn ti bẹrẹ si wa ni wọn ri awọn ẹlẹwọn ti nwọn si tun fi ofin miran gbe wọn.

## "Ọrọ Agba Bi Ko Ba Ṣe Lowurọ, A Ṣe L'alẹ"

# AWỌN ALAKOSO IJỌBA FẸ ṢE IPADE BONKẸLẸ

KADUNA:- Ni deede agogo marun irọlẹ ana ọjọ Aje ti iṣe ọjọ kejilelogun oṣu yi ni iroLin de si etigbọ wa pe awọn alakoso Ijọba Ipinlẹ mẹrẹrin Naijiria yio ṣe ipade bonkẹlẹ kan lori bi gbogbo ẹkan ti nlọ lorilẹ ede yi nisisiyi.

Onirohin wa ni Kaduna tawa lolobo pe ipade ti awọn Alakoso Ijọba yio ṣe yi ko ni ṣe alaikoje lori eto Igbimọ oluwadi ẹkunwo owo-oṣu eyiti Morgan ṣe.

Onirohin wa na tun ṣe alaye siwaju pe, ohun ti nwọn o tun ṣe ipade na le lori lẹhin ti ẹkunwo owo-oṣu ti awọn oṣiṣẹ ni eto abo fun Ijọba Alailọba orilẹ ede Naijiria eyiti ko ni ṣe ijamba fun Ijọba loni tabi lẹhin ọla.

Ninu awọn miran ti nwọn yio tun sọrọ le lori ninu ipade na ni gbigba ti Ijọba yio gba imọran oluwadi Morgan eyiti o ti ṣe fun Ijọba nipa ẹkunwo owo oṣu ti awọn oṣiṣẹ, Lẹhinna awọn Alakoso na yio tun sọ aye ti awọn oṣiṣẹ wa ni orilẹ ede yi ati gbogb awọn aṣiwaju wọn.

### IWE AṢẸ

Lori eto abo fun Ijọba alakoso Ijọba kọkan ni yio sọrọ abo lori Ijọba rẹ, nwọn o si ṣe ayẹwo lori



Oloye S. L. Akintọla



Alhaji Ahmadu Bello

awọn eto abo fun Ijọba kọkan.

Irohin fi ye wa pe iwe aṣe eto abo yi ni nwọn o fi lelẹ ninu ipade ti nwọn yio se lori eyiti enikọkan wọn yio sọ ero ati ipinnu wọn le lori, Oniwe irohin wa na ko sọ fun wa ohun to wa ninu iwe na ti wọn o gbe ka iwaju ninu ipade ṣugbọn o fi ye wa pe o dabi ẹnipe ona ti ẹnikẹni ko fi ni ta jamba fun Orile ede yi.

A tun gbọ wipe ọkọ ofurufu eyiti apapọ ijọba ra fun ọlọla Abubakar Tafawa Balewa yio lọ si Ibadan lati lọ gbe oloye S. L. Akintọla, Alakoso Ijọba Ipinlẹ Iwọ Orun ọkọ ofurufu na o tun lọ si Enugun lọ lati lọ gbe Dokita M. I. Okpara Alakoso ipinlọ Ila Orun ile Naijiria, ọkọ ofurufu na yio tun lọ si Ibinni lati lọ gbe oloye Dennis Osadebay Alakoso Ipinlẹ Agbedemeji Iwọ Orun Naijiria.

Irohin fi ye wa pe ohun to jẹ ki apapọ Ijọba ṣe eto pajawiri yi nipe awọn alakoso Ijọba fẹ tete ṣe ipade na laisi idaduro nitoripe, Nwọn ngburo labẹ ilẹpe awọn kan ngbimọ lati doju Ijọba bolẹ ti nwọn o si ṣi awọn Alakoso Ijọba ni idi pada.

Irohin Ijọba ti a ri gbọ ko sọ igbati nwọn o ṣe ipade na fun wa ṣugbọn onirohin wa kan fi ye wa pe ni deede agogo mẹwa owurọ yi ni nwọn o ṣe ipade na.

Siwaju si i, a gbọ pe nwọn fẹ ṣe eto fun gbogbo ohun ti awọn oṣiṣẹ nbere ki nwọn o si mọ bi Ijọba o le ṣe e tabi nwọn ko ni le ṣe e fun wọn.



Dokita M. I. Okpara

Lẹhin eyi ni awọn Alakoso Ijọba na yio gbimọ pọ lati fi ero ṣọkan lori ohun ti Ijọba oṣe fun awọn oṣiṣẹ lori ibere wọn, ki o ma ba jẹ wipe ohun ti Ijọba kan o ṣe yio yatọ si Ijọba keji. Nwọn fẹ ki gbogbo Ijọba fohun ṣọkan lori iye owo ti nwọn o fi kun fun awọn oṣiṣẹ.

Onirohin wa kan ran wa-



Alhaji Abubakar Balewa

eti pe, Dokita Michael Okpara lo ti kọkọ kesi ọlọla Alhaji Abubakar Tafawa Balewa pe ki o tete pe ipade awọn alakoso Ijọba lori eto idaṣẹ silẹ awọn osiṣe ni asiko ti awọn oṣiṣẹ fi daṣẹ silẹ sugbọn Abubakar ko ṣe bi enipe on gbọ ọrọ na nigbana.

Ṣugbọn nisisiyi imọran ti Abubakar ko gba tẹlẹ lo wa gba nisisiyi lati pe ipade awọn Alakoso.

### OWO OṢU

Iwe irohin kan sọ ni Eko lana pe awọn oṣiṣẹ ijọba ko ni ri ọwo ọṣu wọn gba ni ipari oṣu yi pe o di inu oṣu ti nbọ ki nwọn to ri owo oṣu won gba nitori iṣẹ ti awọn oṣisẹ da silẹ.

Irohin na wa pari bayi pe, bi oṣu ba ti pari ni gbogbo awọn oṣiṣẹ yio si gba owo wọn Ijọba ko ni fi owo na jafara rara

Ohun ti awọn Alakoso Ijọba na ba sọ ni owurọ oni ẹ si tun ma gbọ ninu iwe irohin wa lọla.

# ITAN AJIRAN ILU AWỌN OKU (Apa 21)

**Lati Ọwọ J. O. Shoyinka**

Nwọn ki i si ba ẹnikẹni sọrọ nwọn le ẹyọ owo silẹ nidi ọja"kọọkan lati le fi mọ iye owo ti nwọn ta a. Onjẹ wọn pọ tobẹ gẹ ẹ ti o fi jẹ pe ẹba ẹnikọbọ (1d) ti wọn ra to gbogbo wọn j ẹ ṣoku nigbati odi agogo mẹta oru ọja tu ero wọn nipe larọ ọjọ keji nwọn yio ma ri enia basọrọ. Sugbọn nwọn ko ri ẹda alaye afi awọn ile sugudu-sugudu larin ilu. Nigbati nwọn ko ri ẹnikan o di bo lọ ọ o yago fun mi Biii ti nwọn yi si ẹhin ọja ni nwọn kan agbole miran.



AWORAN OKE YI NI TI AJIRAN ILU AWỌN OKU

Akọle yi ni nwọn kọ si ẹnu Bode Awọn ọmọ wẹwẹ, ti nwọn wa jaiye ori wọn jẹẹ' ti awọn ọmọ araye ran pada si ọrun apanpadodo awọn wọnyi wa ni agbede meji ọrun ati aiye wọn ko le de ọrun alageji.

Ogbojulogun kan ilẹkun nwọn awọn si wọle

Bi nwọn ti wole nse ni awọn ogowẹrẹ nwọn yi sebi Obirin ni wọn. Nwọn fẹ ko si wọn ninu lati le bi nwọn, pada s'ile aiye, nigbati nwọn si ri pe okunrin ni wọn, nwọn ko ekenna bo awọn ọmọ onilogbo gbogbo ara wọn wa ri patipati bi ẹniti a ti ngna ni paṣan lati ijẹta ara bẹrẹsi ta nwọn gbo o.

Nigbati nwọn ko mọ ohunti nwọn o ṣe, ni nwọn ba me họ, are ọjọ na le ju eyiti ehoro fi sa wọ ina lọ Bi wọn ti nsa lọ, ni awọn ọgo wẹrẹ nsare tẹle wọn. Igbe ẹ gba wa o! ẹ gba wa o!! gba ilu kan.

Nigbati Ayunọrunbọ tun ri hilahilo wọn, anu ṣe e o wa lati ran wọn lọwọ bi o ti yọ si wọn, awọn ogo wẹrẹ duro jẹ, nwọn ko le le awọn ọmọ Onilogbo mọ Ayunọrunbọ bere ohunti o ṣẹlẹ ti nwọn fi nle awọn ọmọ Onilogbo.

Ayunọrunbọ o ṣe pupọ bi ko ba nidi, ẹsẹ ki sẹ lasan Awọn ẹda ọmọ Adamọ lo ran wa s'ọrun npapa ndodo jẹjẹ lawa jaiye ori wa nwọn ko jẹ ẹ ẹlomiran jọmọ ọdun mẹta, omi ran ẹwẹ j'ọmọ ọdun mẹrin. Ọlọdun marun ko niyo ninu wa Nwọn ran wa s'ọrun airotẹlẹ, a ko si laiye, a ko d'ọrun, iru oro dida wo le yi nwọn da baba ati iya wa loro ni ile aiye nwọn sọ wọn di alailọmọ Ayunọrunbọ tẹti ki o gbọ, ẹsun iba ke loni o ti ki ba ṣe tirẹ, "Toripe ninu iran wọn ni yi sibẹsibẹ nwọn ki yio lọ lai jiya."

Bi awọn ogo werẹ tipakuru mọ, ni Ayunọrunbọ ba fi iyẹ na wọn loju, nwọn si sa lọ. Ọkan awọn ọmọ Onilogbo ko balẹ, nitoripe nwọn fẹ tete ri baba wọn ni kia-mọsa, toripe awọn paapa ti mọ daju pe, awọn ti wọ ilu Ajiran, sugbọn ki ẹnikẹni to le ri enia ni ilu Ajiran, ọba ni lati mọ Oluwarẹ.

Ile ọba Ajiran dara pupọ o dabi alujanna wiwo rẹ, nṣe enia loju wẹlẹwẹlẹ, jigi ni nwọn fi ṣe ita rẹ, awọn ododo Ọlọrun didun li o yi afin rẹ ka, gbogbo rẹ nta sansan, o si fa enia mọra agbara oku, ẹfọnran iha, pari, dangboroko ojugun ni nwọn fi mọ ara ogiri afin na; Ogbojulcogun kan ilẹkun asọna si i o bere si bere ọrọ lọwọ wọn.

Asọna bẹrẹ lọwọ awọn ọmọ onilogbo ohun ti nwọn nwa. Nwọn si da lohun pe nwọn wa baba wọn wa si ilu Ajiran ni, o ni nisisiyi nga ko nyin lọ siwaju ọba lati sọ ohun ti ẹba wa ẹ tẹle mi, nwọn si tẹle e.

Ọba ki nwọn dada, o ni ẹnyin alejo mi nibo ni ẹ ti wa? Ibo li ẹ nlọ? Kini ẹ nlọ ṣe nibẹ? ẹ dami lohun ọjọ nlọ" Ige ni "Kabiye Alaiye luwa Alaṣẹ, ekeji oriṣa kade pe lori, ki bata pẹ lẹṣẹ ẹniti o ba ni tirẹ bawo, ogun awọ yio fi ẹjẹ rẹ dandandan Gbogbo awọn ẹmẹwa ọba ni Aṣe Aṣẹ o ni awa nti ile aiye bọ o si wa si ilu Ajiran lati f'oju ganni baba wa onilogbo Ariwa joye ọba ọba atata ẹniti o nfi ilẹ bora lojiji ọrọ ko ju bayi lọ igba keji orisa"

Ọba paṣẹ pẹ ki alagogo ilu kede pe ni ọla on fẹ ri awọn ara ilu yi pata-pata nitoripe awọn ajeji wọlu, nwọn ti fẹ ba wọn sọrọ ṣai ti ilẹ ọjọ keji ti mọ, awọn ara ilu Ajiran ti pejọ siwaju Ọba, o pẹ ki awọn ọmọ Onilogbo to ji nitori wahala wọn ti pọ ju lati ẹhin wa.

Oju Orun ni wọn ti lọ ji wọn, o si ṣe amọna wọn de iwaju Ọba, nigbati nwọn de'le Ọba, nwọn nwo ko-o-ko-o bi adiẹ ti o wa ninu agọ fun ọjọ pipẹ o si tun ohun iyalẹnu lati ri pe awọ enia pọ to bẹ ẹ.

O ni ẹku ijoko ẹnyin ẹnia mi, ti ko ba nidi nko le pe nyin lasan, awọn alejo yi li o wọ ilu li oru ana, aṣọna si mu wọn wa si ọdọ mi, ni ṣoki, nwọn ni Onilogbo ni awọn wa de ihin. Tani ninu nyin ti o njẹ Onilogbo? nwọn nwo ara wọn loju, ko si ẹnlti o wipe on njẹ bẹ ẹ.

Ọbatun bere pe talo tun ku lẹhin? Nwọn ni igbakeji rẹ ni, o ni ki nwọn lọ pe e wa nigbati o de, o bere lọwọ rẹ pe tali o njẹ Onilogbo, o si da Ọba lohun pe on lo njẹ bẹ ẹ. Ẹnu ya Ọba nitoripe ko mọ pe bẹ li o njẹ. Ọba paṣẹ fun awọn ilu pe ki nwọn tuka, nwọn si parẹ bi ọgan.

Ọba Ilu Ajiran sọ fun Onilogbo pe, awọn ọmọ rẹ ni yẹn, mo tọrọ garafa lọwọ nyin, emi nlọ niyẹn. Ọba Ajiran yẹra, ki o ba le ba wọn sọrọ, ko mọ awọn ọmọ rẹ mọ ohun ti o jẹki o le fi mọ wọn ni ila ọmọ (Tribal-Marks) ti o wa lara wọn, nitoripe awọn ọmọ Ọba li o ma nkọ iru ila bayi.

Nigbati Onilogbo ri awọn ọmọ rẹ, ko mọ wọn mọ. O nbere ara wọn lọ wọ ara wọn. Awọn ọmọ rẹ rẹrin musẹn. Ige akọbi Onilogbo daa lohun wipe, awọn na niyi. Inu rẹ dun gidigidi, o ni ẹnyin ọmọ mi, ẹ lọ s'ori ẹni nihin, o tẹrẹ si fi ọwọ pa Ogbojuleogun lori nitoripe abigbẹhin rẹ ni iṣe.

Onilogbo bẹrẹ ọrọ rẹ, oni ẹnyin ọmọ mi ọwọn inu mi dun lati ri nyin, Onikọ Iku jiṣẹ nyin fun mi ara mi ko gba a, nigbati mo gbọ nipa idamu ti o de ba nyin, Oku diẹ ki i roju kan alaye ni nba ti wa f'oju kan nyin, ki idamu nyin ba din ku lo ṣe mu mi ran Onikọ Iku si nyin fun iranlọwọ. Ẹku wahala ọna, ẹku ewu, ija dopin, Ogun tan, ẹ ti ja, ẹ ti jagun mo'lu. Ẹ ma yọ idẹra de ba nyin lati oni lọ

Onilogbo sọ fun awọn ọmọ rẹ pe, ti nwọn ba de ile aiye, tarata ti nwọn ba nlọ, ẹhinkule ni ki nwọn kọkọ gba wọle, nwọn yio ri ikoko rugudu kan ni idi igi Ọṣe, ki nwọn sin nwọn yio si ri iho kekere kan ti ojin lọ jingbun, ninu iho yi ni awọn nkan ini on wa, eeṣin ko le gba oju iho yi wọle anbọsibọsi ọmọ enia.

# IWE SI OLOTU

## Ọdẹku, Ẹ Kilọ Fun Wọn O

Mba ṣopẹ bi Olotu Irohin-Imọlẹ Ọkanṣoṣo ajanaku ti nmi igbo kijikiji ba le gba mi laye lati pe akiyesi Ọgbẹni J. A. Ọdẹku ti iṣe Alakoso Igbimọ ti nmojuto bọsi Munisipa Eko si iwa ti awọn agbero Ọkunrin ati Obinrin nhu si awa ero inu ọk ọ bọọsi.

Iwa ti ọpọlọpọ awọn agbero na hu si awọn ero inu ọk ko dara to, nitori a nfẹ ki Ọgbẹni Ọdẹku ba wa ri si eyi, Ki o si ṣe kilọkilọ fun awọn agbero Ọ unrin ti Obinrin wọnyi lati ma huwa ti o dara si awọn ero inu ọkọ.



Ọgbẹni Julious Ọdẹku

Ẹ ṣeun o mo dupẹ pupọ fun aye ti ẹ gba mi.

Emi ni
Latifu Babalọla
EKO.

## Awọn Ọba Nṣeln bi ?

Ko si ojulowo ọmọ Yoruba ti inu rẹ yio dun si iwa ti awọn Ọba mẹwa ninu awọn Ọba ilẹ Yoruba hu nipa si olori ẹgbẹ Alakukọ ti o Si tun jẹ alakoso Ijoba Ipinlẹ ila Orun ti nwọn ni ki o mọ wa pe ti o ba wa ija le ṣẹlẹ.

Ṣe ki ise ana tabi oni ni olori ẹgbẹ alakukọ ti nwa si Ipinlẹ na a ko si gbọ pe ija bẹ silẹ ri se baba ni ẹyin Ọba je fun gbobgo enia nkan ti ẹ ba se niwipe ki ẹ kilọ fun awọn Ijọba Ipinlẹ Iwọ Orun ki wọn fi ọwọ ọmọ bọsọ

Mo bẹ ẹnyin Ọba ki ẹma fi ọla nyin wọlẹ mọ, ẹnivin ni ẹni gbogbo wa, se nigbati Dokta M, I. Okpara se ibẹwo na njẹ ija bẹ silẹ bi! Nitorina, ẹjọwọ. oju nti awa ọmọ nyin, ẹba wa je mọ Ọlọla Okpara na lọ osi gba ẹyẹ awọn ọmọ Yoruba si gba ni alejo to wipe, on na ko nigbagbe.

Ẹku isẹ ẹniyin ọmọ Yoruba ẹ jọwọ pe, ẹniyin gan ni ẹ wa nsọ kan ile-Naijiria

Emi ni
E. A. Lisdi
Oshogbo

## Itan Ilu Omupo Nko?

Olotu Kara o le o, ẹ jọwọ ẹ maṣe alai ko gba mi laye diẹ ninu iwe nyin oloyin momọ lati kesi awọn agbagba ilu Omupo ki awọn fun wa ni itan ilu Omupo ninu iwe Irohin-Imọlẹ ti o ngbẹnuṣe fun gbogbo awa ọmọ Karo Ojire paapa julo awa ọmọ oju!-ọmọ Igbomina.

Gẹgẹbi ẹuyin agbalagba na ti ma npa lowe pe bi ọmẹde ko gbọ itan,agbọ aroba, totọ ose bi owe ẹ jọwọ ẹ bawa se wadi itan ilu wa yi fun anfani gbogbo wa ati paapa fun awọn iran ti o si mbọ lẹhin ki awọn na le tun ma ri ohun kọ awọn iran miran.

Ni Ipari ọrọ mi mo bẹ ẹnyin agbagba ilu Omupo lati tete ba wa fi itan iṣẹdala ilu wa na ranṣẹ si Olotu o.

Emi ni
Emmanuel Alẹṣinloye
OMUPO.

## Mo Dupẹ Olotu

Inu mi dun pupọ nigbati mo ri aworan mi ti mo gun kẹkẹ elẹin mẹta ninu Iwe Irohin Imọle yọ.

Nko tilẹ tete ri ṣugbọn awọn ọmọ ile wa ti n ọn jẹ ọrẹ mi pei, awọn tisa wa ti nwọnfi kan ma pẹlu oun ni ni mo si fi da tisa wa kan lohun nigbati o bere lọwọ mi pe, Bọsẹde lawo ni aworan rẹ ti ṣe de inu iwe Irohin Imọle mon dalohun pe, ore baba mi ti iṣe Olotu Iwe Irohin na ni o ṣe paramu ti o fi le Jade o gbogbo awọn ọrẹ mi ti nwọn wa ba mi ṣe aṣeye ọjọ ibi mi na ni nwọn ra Iwe Irohin Imọle kọọkan fun iranti'



Omidan Bọsẹde Shoyinka

Olotu iwaju ni opa ebiti ayin o ma re si, Iwaju ni ẹ o ma lọ o Baba, Iya Kehinde ati Iyabọ ki yin pe ẹ ṣeun o.

Emi ni
Bọsẹde Shoyinka
Itirẹ


## Iwọ Ha Fe Kọ Ile Bi ?

Bi o ba fẹ ra ilẹ tabi o fẹ ta ilẹ tabi boya o fẹ kọ ile.

Tete kọwe si wa fun gbogbo awọn ohun ti o ba nfẹ.

Bi o ba kọ ile, a le ma a ba ọ gba owo lọwọ awọn olugbe ile rẹ kia kia, ki owo na a si tẹ ọ lọwọ ni asiko.

Tabi ti enia ba je ọ lowo ti ko san, kọwe si wa, were ni a o ba ogba a lọwọ rẹ

Fun ẹkunrẹrẹ alaye, kọwe siwa, ki o si dan wa wo lẹ ẹ kan ṣo ṣo a o si fi ohun gbogbo tẹ ọ lọruu

J.O. Shoyinka.
General Manager
1, Ishiba Street
Itirẹ—Yaba



AWỌN EGBOGI ATAMATASE PATAKI TI ODAJU LATI ILU JAMANI FUN ITỌJU ARUN ARA ATI OJU-DIDUN PẸLU EKINI:-

## SEDO – PAYAL



(IPARA BI ORI)

Jẹ ojulowo egbogi lati fi ṣe iosan orisirisi arun awọu "ARA" gbogbo ti o ba mba enia ja lara tabi o de ara gẹgẹbi ọwọ ẹsẹ tabi ara hihun tabi didun nigbakugba Inarun tabi akọ Inarun, Ewo, Rorẹ kakiri oju, Ela lapa lapa Ara sisu Alefọ Ekusa lori ọmode tabi agbalagba egbo ẹsẹ tabi Adaajina egbo ẹsẹ ati orisirisi awọn amodi tabi awọn arun ara omiran gbogbo.

BẸNA SI EGBOGI.

Dara pupọ julọ fun awọn ti amodi ti a darukọ wọn si oke iwe yi ba nyọ lẹnu nitoripe iṣẹ rẹ ni lati ma mu gbogbo awọn "kokoro" buruku gbogbo ti o ba wa ninu "ẸJẸ ARA" enia, san patapata a si ma ṣẹ iṣẹ ribiribi ninu "oju" enia pẹlu. Awọn ti oju wọn a ma "nsu" tabi wo baibai tabi ti wọn ko le riran daradara lati ọna jinijini tabi ti o bdal ẹnipe nkankan wa afara si oju wọn yio bẹrẹ si riran Kedere.

Bi o ba ti le gbiyaaju lati ma lo egbogi Jamani yi dede fun igba diẹ alafia yio de si ọ ju gbogbo rẹ lọ egbogi Furunculosin yi a tun ma mu igbọuṣẹ wọrọ wọrọ wa fun awọn ti inu wọn bale tabi ti wọn ki rigbọnṣẹ dede lojojumọ tabi ti igbọnṣẹ wọn mọ nle korokoro nipa bayi jẹdijẹdi a bẹrẹ si ma yọ wọn lẹnu bẹni o si dara fun lilo fun awọn onijẹdijẹdi pẹlu awọn egbogi meji yi yatọ si gbogbo awọn rọbirọbi ti wọn nta kakiri Ṣọbu ilu Eko ati igberikọ Bere wọn ni Ṣọbu awọn:-

Waterloo (P. A. T.) Medicine Stores
8 Palmchurch Street, Itafaji Lagos
NIGERIAN MEDICINE STORE
Tinubu Square Lagos.

Waterloo Medicine Stores
8, Palmchuich Stireet, Lagos
Phone: 22878 Nigeria, (Ọja Ita Faji
AdedunChemist 4 Wakewa Srteet Yaba
ATI AWỌN ṢỌBU
IṢẸ OLODUMARE DISPENSARY OKE BỌLA
IBADAN

## Awọn Olukọ Fẹ Se Idanwo

IBADAN:- Alakoso eto ẹkọ ni Ipinlẹ Iwọ Orun Naijiria si ti kede akoko ti nwọn yio ṣe idanwo awọn akoko iṣẹ Olukọ ti Olupo keji Akoko ti awọn ti yio ṣe idanwo ni agbegbe Eko yio bẹrẹ ni ọjọ kejidinlogun titi di ogunjọ oṣu kọkanla ọdun yi awọn ti Ipinlẹ yio bẹrẹ ni ọjọ kẹrinlelogun oṣu kọkanla titi di ọjọ kẹrin oṣu kejila ọdun yi.



Ogbẹni Olumofin
Minista Alamojuto Eto Ẹkọ

Awọn ti ko ṣe dada ninu ọdun to kọja ti nwọn si fẹ tunṣe lati kọ iwe si (West African Examination Council Form Tcihre) igbimọ ti idari idanwo fun ekun rẹrẹ nipa idanwo tabi lọdọ Ọga ile ẹkọ ibi ti o ti jade ile ẹkọ tabi lọdọ Olubẹwo eto ẹkọ nipa alaye fun eto idanwo na

Nwọn lati da eto ilana nipa idanwo na pada si Akọwe agba ti ile iṣẹ alakoso eto ẹkọ tabi si Ọga ile ẹkọ ti nwọn ti jade tabi olubẹwo ile ẹkọ ki o si de ọwọ wọn ki o mi pẹ ju ọjọ kọkanlelogun oṣu keje ọdun yi

# Yẹ Irawọ Rẹ Wo

AQARIUS (Jan 20 - Feb 18) Edekoyede kan yio besilẹ ninu eyiti iwọ yio fẹ lati ṣe idajọ ti ko tọ suna lẹhin eyi gbogbo nkan ti o ba tun ṣe ni yio ma ba ode paṣẹ.

PISCES (Feb 19 - Mar 20 Gbogbo nkan ti o bajẹ ti awọn ẹlẹgbẹjẹgbẹ ire ni yio ma tidi rẹ bọ. Ori rẹ yio pe nipa ti iṣẹ, iwọ yio si fi ọgbọn parọ ọgbọn lọdọ awọn ọrẹ rẹ.

ARIES (Mar 21 - April 19) Iṣẹ ti o nṣe, yio nira diẹ fun ọ ni akọko bẹrẹ, ṣugbọn yio rọrun fun ọ ni ọsan gangan. Bi iṣẹ rẹ ti pọ to loni, ko ni ṣalaisi ohun ikọṣẹ diẹ. Maṣe binu tu idi asiri ọrọ kan silẹ.

TAURUS (April 20 - May 20) Maṣe ṣori kunkun, ki ṣe ojojumọ ni a fi nri ọsọ ẹni, ojojumọ ko ni ọdun Bi akoko ba to ẹnikan ko ni juwe fun ọ ki o to mọ, fi ọkan balẹ ṣọ alafia ara rẹ na.

GEMINI (May 21 - June 21) Irohin ayọ ni yio gbe iṣẹ ti o ṣẹṣẹ bẹrẹ lẹsẹ Aje yo ma jẹ tirẹ ati alafia ara rẹ. Ma mura nitori irin ajo nbẹ lẹsẹ rẹ ṣugbọn maṣe gbagbe awọn olufẹ rẹ rara.

CANCEL (June 22 - July 22) Dipo ki ara rẹ ma wuwo, ọfẹrẹ gẹgẹbi alafia yio to ọ. Iwọ yio rin irin ajo kan laipẹ yi lọ ki o lọ rọju diẹ lọdọ ọrẹ rẹ ti o fẹran

LEO (July 23 - Aug 22) Iṣẹ pọ fun ọ ti o ni lati ṣe, o si dabi ẹni wipe, iwọ ko mọ ibiti a le bẹrẹ. Maṣe feti si imọran ti awọn mba ọ gba, ero ọkan tirẹ ni ki o ṣe.

VIRGO (Aug 23 - Sept 23) Lọ foju si ohun ti o ma nṣe nṣẹ lojojumọ fi ọrọ nla ti o mbẹ nilẹ silẹ loni, ohun kan yio yọju larin awọn ẹbi rẹ.

LIBRA (Sept 24 - Oct 23) Edeaiyede yio ṣẹlẹ larin awọn ẹbi rẹ, nṣe ni ki o ṣe suru, lọ ri ọlọrọ rẹ yio dara.

SCORPIO (Oct 24 - Nov 22) Iwọ yio ri ere nla jẹ ifẹlọrun yio si wa larin awọn ẹbi rẹ, fi idunu gba ipe ti nwọn o pe ọ sibi ase kan.

SAGITTARIUS (Nov 23 - Dec 21) Tẹra mọ iṣẹ rẹ, ko si ṣiṣẹ ti awọn ajeji enia ko wa fun ọ ati eyiti awọn ijimi enia ko wa fun ọ pelu, ṣe e daradara.

CAPRICORN (Dec 22 - Jan 19) Ṣọra, ki o maṣe ohun ti ko to si itu rẹ lati ṣe, jẹki ọrọ ara rẹ tabi ti ẹbi rẹ jẹ edun ọkan rẹ, ṣiṣe gbogbo enia ki o ba le bori awọn iṣoro ti o ndi ọ lọna lọdọ awọn ọrẹ rẹ.


## MODUPE PRINTING PRESS

LEADERS IN MODERN PRINTING

*Many Firms Patronise* MO*DUPE PRESS*
Because Of *Their:—*
MODERATE CHARGES
EFFICIENCY
GOOD PRINTING
IMPERISHABLE RECORD
DELIGENT SERVICESO
ACCELERATIVE METHODSO
PRINTING
*For Your Next Printing Jobs:—*
Just Call 21985 - Leave the rest to Modupe
We Guarantee Neat Work And Quick Service

**Modupẹ Printing Press**
**16, Bamgbose Street,**
Phone 21985, Lagos.



## Awọn Ọja Ajẹbidan

Iwe ilana Ifa Iyanrin titẹ Etutu sise iwosan ati egbogi ajẹbidan ti o ba ni iwe yi lọwọ, abiku ko ni yọọ lẹnu mọ oso ati ajẹ ko ni lagbara lori rẹ, owo paapa ko ni wọn ọ ohunkohun ti oba si dawọle rere ni yio ja si awọn babalawo ti o ngbowo gba asọ lọwọ enia ko ni ri ọ mọ, iye owo 20/-

Iwe egbogi ajẹbidan Agbabiẹtu awọn Ogun Ajẹbidan ti o wa ninu iwe yi ko ṣe sọ a fi ti o ba raa, ti o ba ni iwe yi lọwọ ṣaṣa ni aruntí o ko ni le wo ko si ni ijaya pe arunkarun tabi asasi kan le pa ọ mọ. Iye owo 25/-

Turari Ẹyọnu Ajẹ ti o ba nfin turari yi ba a ti ṣe ṣalaye rẹ Ajẹ ati abatẹnijẹ ko ni foju si ọ lara ohunkohun ti o ba si dawọle rere ni yio maa ja si, iwe ko ni mọ aita ọja agbana ko si ni wọ igba rẹ idabobo yio si wa fun iwọ ati awọn ẹbi rẹ.

| | |
|---|---|
| PaKngolo kan | 10/6d |
| Iekere | 2/6d |
| we Gbedegbẹyọ Hausa | 3/- |
| Itumọ JosẹfuAlila | 5/- |
| Itumọ Ami Ara | 3/- |
| Eewo ile Yoruba ati Etutu | 4/6d |
| Afọṣẹ Iṣẹdalẹ Yoruba ati Psalm Ajẹbidan | 3/6 |
| Lilo ati agbara Psalm Iṣẹgun lori awọn Ajẹ pẹlu Turari | 30/- |

## APEJUWE ILE IṢẸ WA

Wọ Bọọsi ti o nlọ si Lawanson ni Yaba 3d pere ni, ti o ba sọkalẹ ni Lawanson, bere Ilu Itirẹ. Ti o ba de Ilu Itirẹ bere ibiti nwọn ti npa malu, titi ibẹ ni ile itawe wa wa. Ti o ba fẹ fi owo ransẹ fun ọja ẹ. Adirẹsi mi niyi:—

**J. O. Shoyinka**
c/o Postal Agent
1, Isiba Street,
Itirẹ Via,
Suru Lere, Yaba

Akiyesi Pataki:- ale ri awọn iwe wọn yi ra ni garej Iddo, Mushin, Ikorodu road ati ni gbogbo ile itaja iwe Ti o ko ba ni ra wa si ọdọ mi ngo ta fun

# Fani 'Alagbara'

## Lati Ọwọ Ajẹgboro-Dagba

Gẹgẹbi mo ti gbọ pe nigbati Oloye Fani—Kayọde nlọ si ilu Oyinbo, o sọ ni ibudo ọkọ-ofurufu pe on ti sọ fun awọn enia on ni Ile Ifẹ ki nwọn o maṣe jade nigbati Dokita Okpara ba bẹ Ile-Ifẹ wo.

Iru ọrọ bayi a ma jade lẹnu awọn enia ti a le pe ni alai mọ oore. Fani ko fẹ ki awọn enia rẹ ri Okpara nitori ki nwọn o ma ba yẹ Okpara na si.

Bẹsini Okpara ni ẹniti o jẹki gbogbo enia ma pa Fani-Kayọde ni alagbara loni ti o si sọ di enia iyi ni Ipinlẹ Iwọ Orun, Bi o tilẹ jẹpe Fani-Kayọde tun wa pada lo agbara na lati fi pa Ẹgbẹ N.C.N.C. ati Dokita alara na run ẹniti o sọ di Oloye loni.

Nigbati gbogbo nkan fi le fun Oloye Fani Kayọde ti Akintọla si nfi iya jẹ awọn enia Ile-Ifẹ ṣebi nitṣe ni, Fani-Kayọde salọ si Amerika ti o ni on nlọ kọ nipa bi a tiṣe iṣe aṣiwaju ẹgbẹ Oṣelu ti o si fi awọn enia rẹ silẹ ti Akintọla si nje wọn ni ya.

O wa si ọkan mi lati ronu pe boya awọn enia Ile-Ifẹ gọ ti nwọn o fi ma tan nwọn jẹ nigbagbogbo.

Bi Oloye yi ba ronu jinlẹ ni o yẹ ki o lọ si Ile-Ifẹ ni ki ise ilu Oyinbo ni o yẹ ki o lọ ki on ọẹlu awọn enia rẹ si jijẹ jọko sinu ile ni idi eyi ao mọpe o fẹran awọn enia rẹ bawo ni ẹniti o wa ni ilu Oyinbo ṣe le ran enia ti o wa ni Ifẹ lọwọ Nigbati ibẹ jina pupọ si ile.

Mo fẹ ki gbogbo ẹnyin ti ẹba nfẹ Ijọba idẹra mọ pe bayi ni Fani yio ṣe lọ nigbati iṣoro ba de ba awa ara ilu ti o nṣe Olori fun Nitoripe Olori oṣelu rere ma duro gbọningbọni ti awọn enia rẹ nigba ipọnju ati igba rere nitorina ki Fani-Kayọde ya sare pada wale.

## Adamọdi Ọlọpa Kan Wẹwọn Osu Mẹta

KAFANCHAN:- Okunrin ọdaran Emmanuel Garya eni odun mẹrindinlogbọn sọ ni ile ẹjọ ibilẹ ti Kafanchan pe on fẹran iṣẹ Ọlọpa tabi ki on ma se ọlọpa

Gaiya nsọ eyi niwaju adajọ na nigbati nwọn fi ẹsun pe owọ inu ọkọ oju irin laisan owo ọkọ ati pe o si mu ifere iwe kekere ati ibọsẹ awọn ọlọpa Naijiria lọwọ gẹgẹ bi ọlọpa

Ninu ọrọ odaran na niwaju adajọ, ogba pe on jẹbi ẹsun na ati pe awọn kan ọlọpa lo wa lọwọ on si jẹ ti ẹgbẹ on to jẹ ọlọpa

Ọga Ọlọpa to ngbẹnuṣe fun Ijọba ọgbẹni Salihu sọ fun adajọ ile ẹjọ na pe ki nwọn fi iya to tọ jẹ ọdaran na nitoripe iru ẹsẹ bayi si npọ si bayi,

Ninu ọrọ adajọ na Malamu Dambo sọ fun ọdaran pe iba san ki o lọ ṣe iṣẹ Ọlọpa ju pe ki o fi ara rẹ ma han gẹgẹbi Ọlọpa.

Adajọ na sọ pe O le pada wa ṣe iṣẹ ọlọpa lẹhin ti ọjọ ti yio lo lọgba ẹwọn yio to. Edajọ na si ju Ganyan si ẹwọn oṣu mẹta.

## E Ma a Ka Iwe Irohin Imọlẹ Lojoojumọ Ki ẹ Si Ma Polowo Ọja Nyin Sinu Rẹ Pẹlu


# EGBOGI JẸDIJẸDI

BERE ẸGBOGI



## "CYCLOVEN"

Aworan oke yi fi han gbangba ibiti Jẹdijẹdi rẹ gba wa lara re si nyọ o lẹnu nigbagbogbo. Ibẹ ni a npe ni "omusu tabi iho idi enia ibiti a ma ngbe ṣe igbọnsẹ, Arun Jẹdijẹdi jẹ okan ninu amodi ti o buru ni pataki fun Ọkunrin ti o si lagbara pupọ lati ṣe iwosan rẹ patapata.

Ọpọlọpọ egbogi ni nwọn nta kakiri ode nisiyi ti nwọn ma a polowo wọn fun iwosan rẹ ṣugbọn boya la leri mẹwa ninu awọn ogun ti ole se iwosan arun yi daradara, Awọn ẹlomiran lero wipe boyabi wọn ba lọ si ile lati lọ ke eyiti oba nyọ j de lati omusu ku nipa bẹ awọn o bọ lọwọ rẹ patapata.

Ṣugbọn awa o ro bẹ rara Lẹhin ọdun diẹ iyọnu rẹ ylo si tun bẹrẹ bakana Orişirişi Jẹdijẹdi ni o wa, Ekini ti o bẹrẹ nipa aiko ma ṣe igbọsẹ dede tabi lojojumọ ẹlomiran nipa ijoko ni ojukanna pẹlu lojojumọ tabi gigun kẹkẹ ologere (Basikulu) pupọ ẹlomiran ẹwẹ nipa jijẹ Ṣuga tabi oniruru ohun adidun pupọ pupọju nigbakugba Jẹdijẹdi orişirişi ni o wa, ewo ni tirẹ? Bi o nyọ jade ninu omuṣu tabi ti o ba nmu ẹjẹ wa lẹhin igbọnsẹ tabi ti o ba nyọ ti o ba ṣe igbọnsẹ tan ni tabi ti erin ọ ninu omuṣu ni eyikeyi ti o ba jẹ bere egbogi "CYCLOVEN" ti awọn Oyinbo Jamani ṣẹṣẹ wa idi rẹ kio si danwo orişi mẹta ni daju wipe iwọ ylo bọ lọwọ Jẹdijẹdi patapata alafia yio de si ọ ekeji rẹ ko si ninu gbogbo egbegi atata nigboro Naijiria jakejado bere ni ni:

NIGERIA MEDICINE STORES
4, Tinubu Square, Lagos

Waterloo Medicine Stores
8, Palmchurch Street, Lagos
Phone: 22878 Nigeria, (Ọja Ita Faji

ATI AWỌN ṢỌBU
IṢẸ OLODUMARE DISPENSARY OKE BỌLA
IBADAN



## BI O BA NI
# Iwe—Titẹ

FUN

**Lilo nibi Iṣẹ rẹ tabi orişirişi iwe itufọ tabi ijade Oku**

ATI

**Iwe Igbeyawo**

TETE KỌWE SI ILE–IṢẸ–ẸRỌ ITẸWE

**Modupẹ Printing Press**
16, Bamgboṣe Street, P. O. Box 1495
Telephone: 21985, Lagos.

KETEKETE NI ẸRỌ ITẸWE WA NHAN
OWO POKU NI A SI NGBA
IROHIN KO TO AFOJUBA
*Dan wa wo lẹẹkanṣoṣo ko si ri iyatọ*

# IROHIN IMOLE

IMOLE ORE AIYE, TENI GBOGBO LAWA

No. 726 TUESDAY JUNE 23, 1964 (2D)


## Awọn Ọmọde Meji Kan Jẹun Yọ S'Ọrun

AFIKPO:- Idamu nla ba gbogbo enia nigbati awọn ọmọ iya meji kan Ogbonna Mgbeke eni Ọdun mewa ati aburo rẹ Nwam eni ọdun mẹfa ti nwọn ṣubu lẹsẹkẹsẹ ti nwọn si ku lẹhin ti nwọn jẹ iṣu ti nwọn fi ṣe ọdun ni Okpoṣi ni a begbe Afrikpo ni Ipinlẹ Ila Orun Naijiria.

Gẹgẹbi ọrọ ti Oniwe Irohin wa ni agbegbe na gbọ lati ẹnu awọn Ọlọpa sọ pe awọn ọmọ meji na lọ si ile iya wọn agba lọ ba ṣe ohun iṣẹ tinno to ṣẹṣẹ jade ti awọn ọmọ na si jẹ fufu ti nwọn fi iṣu ṣe pẹlu ọbẹ ẹfọ eyiti iya wọn agba ati awọn na si jẹ.

Lẹhin ti awọn ọmọ na jẹ onjẹ na tan pẹlu iya wọn agba ni awọn ọmọ na si bẹrẹ si bi onjẹ na jade lẹsẹkẹsẹ ti awọn ọmọ na ku tẹlẹtẹle ara wọn ni nkan bi wakati meji ti awọn ọmọ na jẹ onjẹ na tan.

Irohin tun fi ye wa lati Nsukka pe Obinrin kan eni ọdun mẹr nd ọlọgọta Obete Eze pe Obinrin na si jona ku ni ọjọ Eti ti iṣe ọjọ kẹkandinlogun oṣu yi ni ile Obinrin na ni Enugu Ezike ni agbegbe Nsukka ni Ipinlẹ Ila Orun Naijiria.

Irohin na fi ye wa pe Obinrin na nikan lo wa ninu ile rẹ nigbati ile na gbina Obinrin na si sare jade ṣugbọn o tun padu wọ inu ile na ni ikẹhin lati lọ ko awọn eru rẹ jade ṣugbọn ki Obinrin na to jade eefin si ti bọ loju to fi jẹ pe ko fi ri ọna jade eyi to jẹ pe obinrin na si fi jona ku.

### Alhaji Adegbenro Sọ Pe :

# Ẹ FI AWỌN ỌLỌPA IBILẸ ṢI ABẸ ỌLỌPA NAIJIRIA

IBADAN:- Adele olori ẹgbẹ Afẹnifẹre, Alhaji D. S. Adegbenro sọ ninu ipade to ba awọn onirohin sọ ni ọjọ ọjọ'Bọ ti iṣẹ ọjọ kejidinlogun osu pe eto ofin rere ati alafia ko si ni Ipinlẹ Iwọ Orun Naijiria bayi.

Alhaji Agbenro si kesi Olotu Ijọba Apapọ ilẹ Naijiria. Ọlọla Alhaji Abubakar lati fi awọn ọlọpa ibile ti Ipinlẹ Iwọ Orun si abẹ akoso ọlọpa ilẹ Naijiria nitoripe aye ti awọn ọlọpa ibilẹ Ipinlẹ Iwọ Orun wa bayi si buru si ti akoko ofin pajawiri.

Alhaji Adegbenro tun bu ẹnu ẹtẹ lu ẹgbẹ Dẹmọ NNDP gẹgẹbi iwa ti awọn ọmọ ẹgbẹ na nda silẹ eyiti nba alafia ilu jẹ ati pe awọn ọmọ ẹgbẹ Demo si nlo awọn ọlọpa ibilẹ gẹgebi olurannisẹ fun ẹgbẹ wọn lati doju ija ko awọn ọmọ ẹgbẹ oṣelu miran ti ko se iwa janduku lati fun awọn ọmọ ẹgbẹ miran ni inira.

Alhaji Adegbenro si tun sọ pe rogbodiyan to wa ni Ipinlẹ na bayi si ti kọja ti nwọn le fi silẹ bẹ ati pe o rọ olotu Ijọba Apapọ lati fi awọn ọlọpa ilẹ Naijiria gẹgebi nwọn ti ṣe lasiko eto ofin pajawiri ni Ipinlẹ na ni ọdun 1962.

Lapa ọtun ati osi Alhaji Adegbenro ni oloye S. T. Ọrẹdẹin akọwe agba fun akoso ẹgbẹ Afẹnifẹre ati Alhaji Busari Obisẹsan ọmọ ile Igbimọ asofin Ipinlẹ Iwọ Orun ati alaga fun ẹgbẹ Afẹnifẹre ni ẹkun Ibadan o si tun sọ pe awọn ọlọpa ti



Alhaji D. S. Adegbenro

ilẹ Naijiria nikan soso lo vege nipa eto ọrọ oṣelu ati pe awọn nikan si ti to lati pa eto ofin ati alafia mọ ni Ipinlẹ Ila Orun.

ALAFIA

Alhaji Adegbenro tun sọ pe ki nwọn si jẹ ki ọga agba awọn ọlọpa ni ọwọ ninu eto iwa janduku ati aiṣi eto ofin rere to bẹ silẹ ni ipinlẹ na lati le pa gbogbo awon iwa iru bẹ yen rẹ

Alhaji D S Adegbenro sọ pe awọn oriṣi ọlọpa meji lo jẹ bakanna ni ipinlẹ Iwọ Orun ati pe gbog'o nkan to nṣẹlẹ ni Iwọ Orun o yato si ti ipinlẹ Ariwa nibi ti awọn Ọlọpa ti ilẹ Naijiria ko ni le lo agbara nwọn gẹgebi o ti yẹ.

Alhaji sọ pe "Awa ọmọ ẹgbẹ Afẹnifere ti gbiyanju ti apa lati le tẹle eto ofin ati alafia ipinlẹ na ati pe ti awọn ọmọ Dẹmọ to jẹ pe nwọn fẹ ma hu iwa janduku wọn ati lati ma a ni awọn ọmọ ẹgbẹ Afẹnifẹre ati Alakukọ lara pe awọn yio gbẹsan ati papa julọ pe yio ju gbogbo bi awọn ọmọ ẹgbẹ na ti ṣe fun wọn tẹle.

IṢẸ OLOTU APAPỌ

Alhaji Adegbenro sọ pe Olotu ajapọ ijọba Naijiria ni iṣẹ gidi lati ṣe ati lati le sọ fun ọga agba ọlọpa ilẹ Naijiria pe ki nwọn tete ṣe alakoso awọn ọlọpa ijọba ibilẹ ipinlẹ ila Orun Naijiria lati le tete ṣe atunṣe eto ofin alafia ipinlẹ na to wa ni idarudapọ bayi.

Gẹgẹbi idahun ti Alhaji Adegbenro nfun awọn oniwe Irohin pe awọn ti ngbọ pe ijọba ipinlẹ na eyiti ẹgbẹ Dẹmọ N N D P nṣe akoso si ti sọ fun awọn ọlọpa ijọba ibilẹ pe gbogbo ẹjọ to ba ti jẹ awọn ẹgbẹ oṣelu tabi ẹjọ miran pe nwọn yio gbe lọ si ile ẹjọ ti ibile.

Nipa bayi Alhaji Adegbero sọ pe nwọn ko ni le jẹ ki awọn ọlọpa ti Naijiria ṣe iṣẹ wọn lọna torẹ ati eyi to si yẹ.

Alhaji Adegbenro sọ pe awọn Ijọba ẹgbẹ Dẹmọ fẹ sọ Ipinlẹ Iwọ Orun di gẹgẹbi Ipinlẹ Ariwa tiri eyi to jẹ pe awọn Ọlọpa Ijọba Ibilẹ ati Ile ẹjọ ti awọn Alikali ti awọn ọmọ ẹgbẹ oṣelu to nṣe akoso Ijọba nibẹ nlo awọn Ọlọpa wọnyi ati awọn adajọ ile ẹjọ Alikali lati fi gbogun ti awọn ọmọ



Ọlọla Nnamdi Azikwe

ẹgbẹ oṣelu miran ti ko ba ti ṣe ti wọn ati lati mu awọn ti ko ṣe ẹgbẹ ti wọn pẹlu agbara lati ṣe ọmọ ẹgbẹ ti wọn.

Nipa eto ti awọn Ijọba Ibilẹ ilu Ibadan nṣe lati gba awọn enia ti yio wa gẹgẹbi awọn ti yio ma sọ ilu to ba si di alẹ, Adele Olori ẹgbẹ Afẹnifẹre sọ pe imọ bu buru ni awọn Ijọba Ibilẹ wọnyi ngbero lati le ri aye pa awọn ọmọ ẹgbẹ oṣelu miran ti ko ṣe ti wọn.

Alhaji Adegbenro rọ gbogbo awọn ọmọ ẹgbẹ Afẹnifẹre ati Alakukọ lati fun ara wọn ṣe oluṣọ ara wọn ati pe enikẹni to ba fẹ ṣe jamba pẹlu wọn pe ki nwọn tete mura silẹ

Alhaji Adegbenro sọ pe fun odidi ọjọ marun ni awọn janduku wọnyi fi gbero lati ba ile Olori ẹgbẹ Afẹnifẹre Oloye Awolọwọ jẹ ati ile iṣẹ awọn ọmọ ẹgbẹ Afẹnifẹre ni Ibadan.


REMAIN YOUNG
100 YEARS
Details:-Add,
C. T. Hospital, (R Y)
Azad Market, Delhi
6 India.



Printed and Published by Modupe Printing Press 16 Bamgbose Street Lagos Phone 21985
Editor:- TUNJI ADEOSUN 45, Campbell Street Lagos 23/6/64